# ITỌJU AWỌN ALUFAA ATI AWỌN ỌMỌ LEFI
## Numeri 18:1-32
### ẸKỌ 98 – FUN AWỌN AGBA

**AKỌSORI: "OLUWA ni ipin ini mi, ati ti ago mi; iwọ li o mu ìla mi duro" (Orin Dafidi 16:5).**

**I Ojuṣe Awọn Alufaa ati ti Awọn Ọmọ Lefi**

1. Ijọsin fun Ọlọrun ni ibi mimọ wa ni ọwọ awọn alufaa, ti yoo maa duro niwaju Ọlọrun fun awọn eniyan, Numeri 18:1, 2, 5, 7; 1 Kọrinti 4:1, 2; 1 Peteru 4:10
2. Iṣẹ awọn ọmọ Lefi ni lati maa ṣe itọju Agọ-ajọ ati lati maa ran awọn alufaa lọwọ ninu iṣẹ miiran gbogbo, Numeri 18:2-4, 6, 21-23; 2 Awọn Ọba 3:11; Matteu 10:42; Marku 10:43, 44

**II Ipese Ọlọrun fun Aini Awọn Alufaa Rẹ ati Awọn Ẹbi Wọn**

3. Fun ounjẹ oojọ wọn, a fun awọn alufaa ni diẹ ninu awọn ẹbọ ti a kò sun ninu iná, ninu wọn ni ẹbọ irekọja, awọn kan ninu ẹbọ ẹṣẹ ati apa kan ninu ẹbọ ohun jijẹ, Numeri 18:8-10; Lefitiku 2:3, 9, 10; 6:16, 23, 25, 26, 30; 7:5-10; 10:12, 13, 16-20; Deuteronomi 18:3; Matteu 10:9, 10; 1 Kọrinti 9:9-14; Galatia 6:6; Filippi 4:14; 1 Timoteu 5:18; Esekiẹli 44:29
4. Owo ti awọn ọmọ Israẹli mu wa fun irapada awọn akọbi ni a fifun awọn alufaa, nitori awọn ọmọ Lefi ni o dipo wọn lati maa ṣe iṣẹ-isin, Numeri 3:44-51; 18:15, 16; Ẹksodu 34:20
5. Owo ti a fi ṣe atunṣe ni a fi fun awọn alufaa, bi ẹni ti a ṣẹ̀ kò ba si láàyè mọ́, tabi ti ko ni ibatan ti o wa láàyè, Numeri 5:8-10; 2 Awọn Ọba 12:16
6. Apa kan awọn ẹran irubọ, irubọ gbogbo akọso ilẹ; gbogbo akọbi ẹran ti o mọ́, ati awọn ti a fi dipo gbogbo akọbi ẹran alaimọ, ni a fifun awọn alufaa fun ounjẹ wọn, ati ti awọn ẹbi wọn, Numeri 18:11-14, 17-19; Deuteronomi 18:4, 5; Lefitiku 10:14; Esekiẹli 44:30, 31
7. Awọn alufaa ko gbọdọ ní ini kan fun ara wọn, Ọlọrun ni ini wọn, Numeri 18:20; 26:62; Joṣua 13:14; Esekiẹli 44:28

**III Ipese fun Awọn Ọmọ Lefi ati Awọn Ẹbi Wọn**

8. Idamẹwa awọn Ọmọ Israẹli ni a san fun awọn ọmọ Lefi lati lò fun itọju ara wọn, Numeri 18:21-24; Gẹnẹsisi 14:20; 28:20-22; Lefitiku 27:30-33; Deuteronomi 14:28, 29; 26:12-15; 2 Kronika 31:4, 5; Nehemiah 12:44; Malaki 3:10; Matteu 23:23; 1 Kọrinti 16:2; Heberu 7:5
9. Awọn ọmọ Lefi yoo fi idamẹwa ninu idamẹwa ti wọn gbà fun awọn alufaa lati ṣe iranwọ fun aini wọn, Numeri 18:25-29; Nehemiah 10:38, 39
10. Eyi ti o ba ṣẹku silẹ ni awọn ọmọ Lefi yoo mu lò bi wọn ti fẹ, bi ẹni pe lati ọdọ wọn wa ni, Numeri 18:30-32
11. Awọn ọmọ Lefi ko ni ini ni Israẹli ṣugbọn a fun wọn ni ilu ni Ilẹ Ileri ninu eyi ti wọn yoo maa gbe ki wọn le maa ba iṣẹ Ọlọrun lọ ni gbogbo orilẹ-ede, Numeri 35:1-8; Deuteronomi 10:9; 12:12, 19; 14:27, 29; 18:1, 2; Joṣua 13:33

## ALAYE

**Iṣẹ Iranṣẹ ti o Lọ́wọ̀**

Ọlọrun yan awọn alufaa ati awọn ọmọ Lefi lati inu ẹ̀yà awọn Ọmọ Israẹli mejila lati maa jọsin fun Un ni ibi mimọ́ Rẹ̀, O si fi wọn si oniruuru àyè gẹgẹ bi ilana Oun tikala Rẹ̀. Awọn iran Aarọni ni Ó fun ni anfaani pataki lati maa ṣe abojuto isin, lati maa ṣe irubọ, ati lati maa fara han niwaju Rẹ̀ fun awọn eniyan Israẹli. Awọn ọmọ Lefi ni O fi iṣẹ riru Agọ le lọwọ ni akoko irin-ajo wọn ni aginju. Nigba ti awọn Ọmọ Israẹli si ti de Ilẹ Ileri, a ko ṣi Agọ nipo kiri mọ, nitori naa a fi iṣẹ miiran ninu ati ni ayika Agọ fun awọn ọmọ Lefi lati maa ṣe. Wọn tọju ofin, wọn si n fi kọ́ ni, wọn n ṣe idajọ, wọn n ṣe iṣẹ-isin ati iyin si Ọlọrun -- ọpọlọpọ ninu wọn jẹ́ akọrin ati alohun elo orin -- wọn di oniruuru ipo ti a kà mọ iṣẹ iranṣẹ lode oni mú (Deuteronomi 17:8-12; 24:8; 27:14; 31:9-13, 26; 1 Kronika 23:17-32; 2 Kronika 29:34) Nigbooṣe a fi iṣẹ omi pipọn ati igi ṣiṣẹ fun lilo ninu Agọ le awọn igbekun kan lọwọ dipo awọn ọmọ Lefi ti a fun ni iṣẹ miiran ti o wuwo ju eyi lọ.

Iṣẹ mimọ́ wọnyii gba gbogbo ipá awọn alufaa ati awọn ọmọ Lefi ati pupọ ninu akoko wọn. Ki wọn ba le ni anfaani lati fi gbogbo ipá ati akoko wọn ṣiṣẹ isin Ọlọrun a pa a laṣẹ pe ki awọn eniyan ti wọn n jọsin fun pese fun aini wọn gẹgẹ bi ilana ti Ọlọrun fi lelẹ. Bi wọn ba ni lati maa ṣiṣẹ lati pese fun aini ara wọn, eyi yoo gba pupọ ninu akoko ti wọn i ba fi ṣiṣẹ isin Ọlọrun. Eyi yoo si mu ibajẹ bá iṣẹ Ọlọrun lai pẹ jọjọ, nitori lai fi gbogbo akoko wọn jì fun iṣẹ Ọlọrun, wọn ko ni le ṣe ohun gbogbo ti wọn ni lati ṣe.

**Ọlọrun Mọ Aini Wọn**

Ọna ti a gbà n pese fun aini wọn mu ki wọn ni anito, ṣugbọn ko pọ to lati sọ wọn di ọlọrọ. Ṣugbọn Ọlọrun ti ṣeleri pe Oun ni yoo jẹ́ ipin wọn; pẹlu ipese kọọkan ti i ṣe ti ara, Ọlọrun fi ibukun ti ẹmi fun wọn ti o mu ki igbesi-aye wọn dùn niwọn igba ti wọn ba sin In tọkantọkan.

Ko si igbesi-aye ti o ni ibukun bi eyi ti a fi fun Ọlọrun patapata. Ko si ayọ ti o le tayọ ti ẹni ti o n sin Ọlọrun "ninu ibi mimọ́ Rẹ̀" tabi ẹni ti o fi aye rẹ jì fun iṣẹ isin Ọlọrun, bi o ti wu ki iṣẹ naa ti rẹlẹ to. Ayọ Ọlọrun ni i ṣe agbara awọn ọkunrin wọnyii ti wọn fi ara wọn jì; nitori otitọ yii si ti fi ara han fun wọn, wọn le jade lati kọ́ awọn eniyan nipa iru ibukun ti o wà ninu majẹmu ileri wọnni, ki gbogbo wọn ba le di ẹni ibukun.

Diẹ ninu ilana ofin ṣe eto fun aini awọn iranṣẹ Ọlọrun wọnyii nigba ti wọn n rin kiri ni aginju, ṣugbọn omiran ninu ofin wọnyii jẹ mọ ti aini wọn ni Ilẹ Ileri, nigba ti wọn ba de ibujoko wọn. Ṣugbọn gbogbo eto wọnyii ni o fara kọ́ isin Ọlọrun. Apọsteli ni sọ fun ni pe Oluwa ti ṣe ilana pe awọn ti o n waasu Ihinrere ni lati jẹ nipa Ihinrere. A ri i pe ninu igbesi-aye awọn Ọmọ Israẹli, awọn kan ti a fi si ipo ọla yii lo o ni ọna ti ko tọ nipa wiwá ère ti ara wọn. Awọn wọnyii ko waasu Ihinrere mọ́ bẹẹ ni wọn ko si sin Ọlọrun mọ́ ninu ijọsin ti ẹmi, ṣugbọn wọn n wá ère fun ara wọn ati ifẹkufẹ ara wọn, wọn si mu ki awọn eniyan korira isin Ọlọrun (1 Samueli 2:12-17, 22-24).

**Ipinfunni gẹgẹ bi Ojuṣe Olukuluku**

Ọlọrun fi apa kan ọrẹ ẹbọ fun awọn ti o ya ara wọn sọtọ fun Un, diẹ ninu eyi ti awọn alufaa ni lati jẹ nibi mimọ, nitori awọn ẹbọ naa jẹ́ ẹbọ mimọ tabi ti etutu. Awọn miiran ni wọn le mu lọ si ile, ki wọn si jẹ ẹ ni ibi ti o mọ́. Lara eyi ti awọn alufaa ni lati jẹ ni ibi mimọ́ nikan ṣoṣo ni ẹbọ ẹbi, apa kan ninu ẹbọ ẹ̀ṣẹ (eyi ti a ko mu ẹjẹ rẹ lọ si Ibi Mimọ́ ki a si fi i sara pẹpẹ wura), ẹbọ alaafia, idi-ọka akọso ikore, apa kan ninu ẹbọ ohun jijẹ, iṣu akara meji ti a mu wa ni akoko ajọ ọsẹ, akara ifihan, ati ororo olifi (Lefitiku 6:25, 26, 30; 7:1-10, 31-34; 14:10, 24; 23:10, 17, 19, 20, 24:5-9).

Awọn wọnyii ni wọn le mu lọ si ibikibi ti o ba mọ́ ninu agọ ki awọn ẹbi alufaa si jẹ ẹ: ẹbọ igbesọsoke, ẹbọ fifi, apa kan lara agbò ti Nasiri, akọbi ẹran ọsin, akọso ohun ọgbin ti a ba kore (Numeri 6:17, 20; 18:11-19).

Awọn ẹbọ miiran wà ti o jẹ pe ni Ilẹ Kenaani ni a gbe bẹrẹ si fi i fun awọn iranṣẹ Ọlọrun ti a ti ya sọtọ gẹgẹ bi Ọlọrun ti lana silẹ; ẹbọ igbesọsoke ti akọso ikore, idamẹwa ibisi ilẹ wọn, akara àtetekọ́ṣù iyẹfun, àkọ́rẹ́ irun agutan; ati awọn ilu ati ilẹ ti a fi fun wọn lati maa gbé (Numeri 15:20; 18:12, 28; 35:1-34; Deuteronomi 18:4; Lefitiku 22:17-25).

Pẹlu ẹbọ wọnyii a tun ya ohun miiran ṣọtọ fun awọn alufaa ati ẹbi wọn, tabi awọn ọmọ Lefi ati ẹbi wọn, gẹgẹ bi aṣẹ ati ilana Ọlọrun. Awọn wọnyii ni a fi fun wọn lati pese fun aini wọn ki wọn si maa lò wọn bi wọn ti fẹ bi ẹni pe awọn tikara wọn ni o gbin awọn ohun-ọgbin tabi ti o tọju awọn ohun-ọsin naa dagba. Awọn wọnyii pẹlu ni wọn si le lo nibikibi ti wọn ba wà: ọrẹ ẹran pipa, owo irapada ti a mu wa lati ra awọn akọbi ninu awọn Ọmọ Israẹli pada (awọn ti o wa fun isin Ọlọrun tẹlẹ tẹlẹ ki a to fi awọn ọmọ Lefi rọpo wọn), ọdọ-agutan ti a fi rọpọ ẹran alaimọ, awọn ohun miiran ti ko ni oluwa, awọn iyasọtọ fun Ọlọrun -- ọkan ninu rẹ ni awọ ẹran ẹbọ sisun ti owurọ tabi ti aṣẹ, tabi ẹbọ sisun miiran ti akanṣe tabi eyi ti a maa n ṣe ni akoko ti rẹ -- ati owo ti a fi ṣe atunṣe bi a ko ba le ri ẹni naa ti a fẹ ṣe atunṣe fun (Ẹksodu 34:20; Lefitiku 7:8; Numeri 5:8; 18:15-19; Deuteronomi 18:3-5). A ki i fi ẹran awọn ẹbọ sisun fun awọn alufaa tabi ọmọ Lefi, nitori a ni lati sun un jona patapata lori pẹpẹ.

Ọlọrun kilọ fun awọn eniyan naa lati ẹnu Mose pe wọn ko gbọdọ gbagbe awọn ọmọ Lefi ti a ti yà sọtọ fun Oun, ti ko si ni ipin tabi ogun ni Ilẹ Ileri (Deuteronomi 14:27; 16:11, 14). A pa a laṣẹ fun wọn lati ṣe itọju awọn ẹni iyasọtọ wọnyii daradara ki wọn si bu ọla fun wọn nitori àyè ti wọn dimu ninu iṣẹ-isin Ọlọrun.

Lọna kan naa ti Ọlọrun gba fi dandan le ijọlootọ si majẹmu ni O fi dandan le e fun awọn Ọmọ Israẹli pe ṣiṣe ojuṣe ti Oun fi le wọn lọwọ lati ṣe itọju awọn iranṣẹ Rẹ̀ jẹ danindanin bi wọn ba fẹ gbadun ki wọn si wà ni alaafia ati ailewu gẹgẹ bi orilẹ-ede tabi ẹni kọọkan. O tilẹ ba wọn dá majẹmu kan ti O pe ni "majẹmu iyọ̀." A lo ede yii nitori gbogbo eniyan ni o mọ̀ pe iyọ̀ ki i jẹ ki ounjẹ bajẹ, paapaa ju lọ ẹran. Bakan naa ni "majẹmu iyọ̀" jẹ majẹmu ti ki i yipada ti o si wà titi lae.

**Ilana Ọlọrun fun Wa ni Ode-Oni**

Igba ijọba Israẹli jẹ apẹẹrẹ fun wa ni ọna pupọ. Awa naa pẹlu le tọ Ọlọrun wa pẹlu ẹbọ ati ọrẹ akọso ti ẹmi lati le ri ibukun ti o daju gba lọdọ Rẹ̀. Ṣugbọn a ko gbọdọ gbagbe pe ohun ti a beere lọwọ wa ni akoko Ihinrere ko kere si eyi ti a beere labẹ Ofin. Igbọran a maa mu ere nla nla ba ni, bakan naa ni aigbọran maa n fa ibinu Ọlọrun ati idajọ ti o daju.

Sisan idamẹwa ibisi awọn Ọmọ Israẹli jẹ dandan fun wọn, gẹgẹ bi awa naa si ti mọ, eyi ni ọna ti a gba n pese fun awọn ọmọ Lefi ati awọn alufaa. Ṣugbọn ki i ṣe igba ti a fun ni ni Ofin ni ọran idamẹwa ṣẹṣẹ bẹrẹ, nitori a ka pe

Abrahamu san idamẹwa ni nnkan bi ẹgbẹta ọdún ṣaaju akoko Ofin; Jakọbu pẹlu si tun ṣe ohun kan naa lẹyin eyi. Nipa bẹẹ wọn fi han pe idamẹwa jẹ ohun ti Ọlọrun ti fi lelẹ ṣaaju akoko ti wọn. (Ka Heberu 7:1-6; Gẹnẹsisi 28:22). Nitori naa idamẹwa sisan gẹgẹ bi ero ti o pilẹ fifi Ofin fun ni ki i ṣe fun awọn Ju nikan, ọranyan ni fun awa ti ode oni pẹlu.

Paulu Apọsteli kọwe si awọn Onigbagbọ ti o wà ni Kọrinti pe, "Li ọjọ ikini ọ̀sẹ, ki olukuluku nyin fi sinu iṣura lọdọ ara rẹ̀ li apakan, gẹgẹ bi Ọlọrun ti ṣe rere fun u" (1 Kọrinti 16:2). Ki i ṣe pe Jesu fi ọwọ si fifi owo idẹ meji ti opo ni mu wa fun Ọlọrun nikan ṣugbọn o yin in pẹlu. Bakan naa ni Jesu tun fi han gbangba pe idamẹwa sisan jẹ ohun ti awa ti isisiyii ko gbọdọ má ṣe, nigba ti O ba awọn akọwe ati Farisi wi nipa sisọ pe, "Egbé ni fun nyin, ẹnyin akọwe ati Farisi, agabagebe; nitoriti ẹnyin nsan idamẹwa minti, ati anise, ati kumini, ẹnyin si ti fi ọ̀ran ti o tobiju ninu ofin silẹ laiṣe, idajọ, ãnu, ati igbagbọ́: wọnyi li o tọ́ ti ẹnyin iba ṣe, ẹnyin kì ba si fi wọnni silẹ laiṣe" (Matteu 23:23).

Ọlọrun ṣeleri ibukun nla nla fun awọn ti o ba gbọran si Ọrọ Rẹ̀ O sọ fun ni pe Oun yoo tu ibukun da le wa lori ju bi a ti le gba lọ, bi a ba bu ọla fun Oun nipa gbigbọran si aṣẹ Rẹ̀ yii. (Ka Malaki 3:8-10). O si tun wi fun ni bayii pe, "Bi ẹnyin ba mọ̀ nkan wọnyi, alabukun-fun ni nyin, bi ẹnyin ba nṣe wọn."

Ẹni ibukun tootọ ni awọn wọnni ti o pa majẹmu Ọlọrun mọ ti wọn si n rin ni ọna Rẹ̀! Alabukun-fun ni awọn ti o n ṣe ifẹ Rẹ̀ ti ko si jẹ kuna lati bu ọla fun Ọrọ Rẹ̀ ni pipa a mọ kinnikinni! Alabukun-fun ni awọn ti o fi ayé wọn jì fun iṣẹ Rẹ̀ ti wọn si gbẹkẹ le E fun jijẹ ati mimu wọn lọjọọjọ, ẹni ti agbara wọn i ṣe ayọ Oluwa ati Oluwa paapaa jẹ ini wọn! Ko si ayọ ti a le fi wé ti wọn, ko si si itẹlọrun ti a le fi wé eyi ti a n ri gba ni ọjọ kọọkan ti a lò patapata fun iṣẹ ṣiṣe ninu ọgbà ajara Oluwa!

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni ṣe ti Ọlọrun fi mu ọran itọju awọn ojiṣẹ Rẹ̀ ni danindanin?
2. Ki ni iṣẹ awọn alufaa?
3. Iṣẹ pataki wo ni a yan fun awọn ọmọ Lefi?
4. Ṣe apejuwe bi a ti n ṣe itọju awọn alufaa, paapaa nipa ipese ounjẹ wọn.
5. Bawo ni ounjẹ awọn ẹbi alufaa ati ohun miiran ti o tọ si wọn ṣe n tẹ̀ wọn lọwọ?
6. Ki ni ilana pataki ti Ọlọkrun ṣe lati ṣe itọju awọn ọmọ Lefi?
7. Ki ni awọn ọmọ Lefi ni lati fi fun awọn alufaa ki a to boju to aini awọn paapaa?
8. Sọ bi a ṣe n ra akọbi awọn ẹranko ti kò mọ́ pada.
9. Ki ni ṣe ti a ni lati ra akọbi ọmọkunrin pada, ta ni a si n fi owo irapada naa fun?
10. Ojuṣe wo ni awọn Onigbagbọ ni lati ṣe ni ode-oni lati pese fun itọju iṣẹ Ọlọrun?